# Gbígbófinró Ìṣíwọ̀lú ní Ibi-iṣẹ́



**Ìtọ́nisọ́nà yìí ó ṣàlàyé kí ni gbígbófinró ìṣíwọ̀lú jẹ́, kí ni yóò jẹ́ ṣíṣe tí wọ́n bá wá sí ibi-iṣẹ́ rẹ, àti bí ọ ṣe lè gbaradì tí ó bá ṣẹlẹ̀ pé ìgbógun wáyé.**

### Kí ni ICE?

- ICE jẹ́ àdàpè fún Àkóso Ìṣíwọ̀lú àti Gbígbófinró Àwọn Kọ́sítọ̀ọ̀mù, iléeṣẹ́ ìjọba àpapọ̀ kan lábẹ́ Ẹ̀ka Ìṣàkóso Ààbò Ìlú (DHS) tó ń ṣe ìdìmúlẹ̀ òfin ìṣíwọ̀lú.
- Àwọn aṣojú ICE jẹ́ aṣojú ìjọba àpapọ̀, tí wọn sì kìí ṣe ọkannáà pẹ̀lú ọlọ́pàá agbègbè. Aṣọ wọn lè sọ pé “Ọlọ́pàá,” “Aṣojú Ìjọba Àpapọ̀,” “ICE,” tàbí “HSI.” Wọ́n sì tún lè máa wọ aṣọ ẹ̀ṣọ́. Wọ́n lè gbé ìbon dání. Nígbà mìíràn ọlọ́pàá agbègbè máa ń lọ fún ìgbógun ICE pẹ̀lú àwọn aṣojú ICE.

### Kí ni ICE máa ń ṣe ní àwọn ibiṣẹ́?

- Àwọn aṣojú ìṣíwọ̀lú lè wá sí ibi-iṣẹ́ rẹ fún àyẹ̀wò Fọ́ọ̀mù 1-9; ìgbógun; tàbí fi òfin mú àwọn ènìyàn kan pàtó.

### Báwo ni àwọn àyẹ̀wò àti ìgbógun ṣe yàtọ̀?

- Pẹ̀lú ìgbógun ICE, agbanisíṣẹ́ náà ò ní gba ìkìlọ̀ kankan. Pẹ̀lú àyẹ̀wò, ìfiwépè sábà máa ń wà ṣáájú. Àyẹ̀wò ICE “kìí wá pẹ̀lú ìkanra” bíi ìgbógun ṣùgbọ́n ó lè yọrí sí àwọn àbájáde búburú.

## Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ lásíkò àbẹ̀wò ICE tàbí ìgbógun

- Ọ ní ẹ̀tọ́ nígbà gbogbo láti dákẹ́ àti láti má dáhùn àwọn ìbéèrè kankan.
  - ICE lè lo àlàyé tí ọ bá fún wọn láti takò ọ́ tó bá yá.
  - Ọ lè sọ pé, “mo fẹ́ dákẹ́” tàbí “Mi ò fẹ́ dáhùn àwọn ìbéèrè.”
- Ọ ní ẹ̀tọ́ nígbà gbogbo láti kọ wíwá ara rẹ tàbí àwọn dúkìá rẹ.
  - Ọ kò ní láti ṣàfihàn àwọn ID tàbí àwọn ìwé kankan sí ICE. Gbogbo ènìyàn ló ní ẹ̀tọ́ yìí.
  - Ọ lè sọ pé, “mi ò fọwọsí ṣíṣe àwárí.”
- ICE ò lè fi ẹnikẹ́ni sí ìdádúró tàbí wọ inú ààyè aládàáni láìsí ìwé-àṣẹ láti ọwọ́ ilé-ẹjọ́.
- Ọ ní ẹ̀tọ́ nígbà gbogbo láti ṣe àkásílẹ̀ àwọn aṣojú ICE àti ohun tí wọ́n bá ń ṣe, níwọ̀n ìgbà tí ìwọ ò bá fa ìdílọ́wọ́.

# ÀWỌN ÒṢÌṢẸ́: Bí a ṣe lè gbaradì fún àvẹ̀wò ICE

## Ṣáájú àbẹ̀wò


- Ní ìgbáradì fún tí nǹkan búburú bá ṣẹlẹ̀.
  - Bá agbẹjọ́rọ̀ ìṣíwọ̀lú sọ̀rọ̀, tàbí farabalẹ̀ lo àkókò rẹ láti wá ọkan.
  - Ní ètò ààbò ẹbí àti ìtọ́jú ọmọ.
  - Fi àwọn nọ́mbà pàtàkì sí àpò ìrántí.
  - Ṣe ìpamọ́ àwọn ìwé àkọsílẹ̀ pàtàkì síbi àìléwu.
  - Ṣe ìpamọ́ owó fún àwọn pàjáwírì.
  - Tí ó bá ṣeéṣe, lọ fún ètò ìfọ̀rọ̀wérọ̀ Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ àti kí ọ sì jíròrò àwọn àlàyé náà pẹ̀lú àwọn alábààṣiṣẹ́ rẹ.
- Mọ kí ni àwọn ẹ̀tọ́ rẹ tó dá lórí ààyè tí ọ wà ní ibi-iṣẹ́ rẹ:
  - Ààyè Àwùjọ
    - Àwọn agbègbè àwùjọ jẹ́ ibi tí ẹnikẹ́ni lè wọ̀ láì gba ìyọ̀nda.
      - Fún àpẹẹrẹ: ààyè oúnjẹ nínú ilé-oúnjẹ: agbègbè ìtajà-rajà ti ilé-ìtajà; ọgbà ọkọ̀; ọ̀dẹ̀dẹ̀ tàbí agbègbè ìdúró sí.
    - Àwọn aṣojú ICE le wọ àwọn agbègbè àwùjọ ibi-iṣẹ́ láì gba ìyọ̀nda.
    - Àwọn aṣojú ICE ò lè dá ẹnikẹ́ni dúró, ṣe ìbéèrè, tàbí fi ẹnikẹ́ni sí àtìmọ́lé nítorí pé ó jẹ́ agbègbè àwùjọ.
  - Àwọn Agbègbè Aládàáni
    - Ẹnìkankan ò leè wọ inú agbègbè aládàáni láì gba ìyọ̀nda agbanisíṣẹ́ tàbí ìwé-àṣẹ láti ọwọ́ ilé-ẹjọ́.
    - Aṣojú ìṣíwọ̀lú lè béèrè fún ìwọlé sí agbègbè aládàáni nìkan tí wọ́n bá ní ìwé-àṣẹ láti ọwọ́ ilé-ẹjọ́.
  - Ṣe àgbékalẹ̀ ètò pẹ̀lú àwọn alábààṣiṣẹ́ pọ̀ rẹ àti agbanisíṣẹ́. Mọ àwọn ibi tí agbègbè àwùjọ àti àwọn agbègbè wà ní ibi-iṣẹ́ rẹ.
- Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ!
  - Ọ ní ẹ̀tọ́ láti dákẹ́ àti láti má dáhùn àwọn ìbéèrè kankan.
  - Ọ kò ní láti ṣàfihàn ohun ìdánimọ̀.
  - Ọ ní ẹ̀tọ́ láti kọ wíwá ara rẹ̀ tàbí àwọn dúkìá rẹ.
  - Ọ ní ẹ̀tọ́ láti má wà ní ìdádúró láìsí ìdí tó fẹsẹ̀múlẹ̀.
  - Ọ ní ẹ̀tọ́ láti ṣe àkásílẹ̀ àwọn òṣìṣẹ́ agbófinró.

## Lásíkò àbẹ̀wò kan

- Farabalẹ̀. Má sáré tàbí farapamọ́ fún àwọn aṣojú. Ìyẹn lè fún wọn ní ìdí láti fi ọ sí àtìmọ́lé.
- Tọ́ka gbogbo àwọn aṣojú àti ìbéèrè sí alábojútó tàbí agbanisíṣẹ́ rẹ.
- Má bá aṣojú kankan sọ̀rọ̀. Ohunkóhun tí ọ bá sọ lè jẹ́ lílò láti takò ọ́ tàbí àwọn alábààṣiṣẹ́ pọ̀ rẹ.
  - Ọ kò ní láti dáhùn àwọn ìbéèrè nípa ipò ìṣíwọ̀lú rẹ, ibi tí ọ ti wá, tàbí bí ọ ṣe ti pé sí ní ibí.
  - Ọ kò ní láti dáhùn àwọn ìbéèrè kankan nípa àwọn òṣìṣẹ́ mìíràn.
- Tí àwọn aṣojú ICE bá gbìyànjú láti wọlé sí agbègbè aládàáni, ọ lè sọ pé: “Ibí jẹ́ agbègbè aládàáni. Ẹ kò lè wọlé láìsí ìwé-àṣẹ láti ọwọ́ ilé-ẹjọ́ l’éyì tí adájọ́ buwọ́lù,” kí ọ sì tọ́ka wọn sí alábojútó rẹ tàbí agbanisíṣẹ́.
- Máa wo ohun tí àwọn aṣojú náà bá ṣe àti pé tí ó bá rọrùn fún ọ, ṣe àkásílẹ̀ fídíò àwọn ìgbésẹ wọn.

## Lẹ́yìn àbẹ̀wò

- Ṣe àkọsílẹ̀ gbogbo àwọn ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé láti ibi ìbáraẹnisọ̀rọ̀ tó pẹ̀lú
  - Àlàyé nípa àwọn aṣojú gẹ́gẹ́ bíi àwọn orúkọ àti àwọn nọ́mbà ìdánimọ̀.
  - Bí wọ́n ṣe ṣàgbékalẹ̀ ara wọn:
    - Bí wọ́n ṣe hùwà àti sọ̀rọ̀.
    - Ohun tí wọ́n wọ̀, bíi àwọn aṣọ àti àwọn ohun ìjagun.
    - Bí wọ́n ṣe hùwà sí gbogbo àwọn òṣìṣẹ́.
- Ṣe ìfisùn ìgbógun náà sí àjọ àwùjọ tó ṣe é gbẹ́kẹ̀lé tàbí ẹgbẹ́, tí ó bá ṣeéṣe.



# ÀWỌN AGBANISÍṢẸ́: Bí a ṣe lè gbaradì fún àbẹ̀wò ICE

## Àwọn ìgbógun ICE

- Lára ìwádìí nípa agbanisíṣẹ́ kan àwọn aṣojú ICE lè lọ sí ibi-iṣẹ́ kan láìsí ìkìlọ̀.
- Àwọn aṣojú ICE lè wá síbi ìṣòwò rẹ láti gbìyànjú láti ṣàwárí èèyàn pàtó kan (tàbí àwọn ènìyàn). Nígbà tí wọ́n bá wà níbẹ̀, wọ́n lè gbìyànjú láti bèèrè ìbéèrè, fi òfin mú ni, àti pàápàá fi àwọn ẹlòmíràn sí àtìmọ́lé.
- Àwọn aṣojú ICE lè gbìyànjú láti dá ẹni dúró, bèèrè ìbéèrè, tàbí pàápàá mú òṣìṣẹ́ kan lọ sí àtìmọ́lé láìsí déédé àṣẹ.

## Àwọn àyẹ̀wò 1-9

- Fọ́ọ̀mù 1-9 jẹ́ dandan fún gbogbo àwọn òṣìṣẹ́.
- Àyẹ̀wò Fọ́ọ̀mù 1-9 jẹ́ nígbà tí ICE bá wá sí ibi ìṣòwò rẹ láti ṣàyẹ̀wò bóyá ọ tẹ̀lé àwọn òfin fún Fọ́ọ̀mù 1-9.
- Fọ́ọ̀mù 1-9 jẹrìí sí ìdánimọ̀ òṣìṣẹ́ àti gbígba àṣẹ láti ṣiṣẹ́ ní U.S.
- Tí kò bá lọ déédé:
  - Tí ICE bá pinnu pé ìṣòwò kan ò tẹ̀lé àwọn òfin Fọ́ọ̀mù 1-9, wọ́n lè dojúkọ:
    - Àṣẹ láti dáwọ́ dúró ìgbanisíṣẹ́ láìsí ìwé ìgbaniláàyè láti ṣiṣẹ́ tó fẹsẹ̀múlẹ̀.
    - Àwọn ìjìyà-ẹ̀ṣẹ̀ àti owó-ìtanràn aráàlú àti ti ọ̀daràn.
- ICE lè fi òfin mú òṣìṣẹ́ kan pàtó nítorí ipò fọ́ọ̀mù 1-9 wọn.

## Ṣáájú àbẹ̀wò

- Ṣe ètò ìdáhùn alákòsílẹ̀ ṣáájú àkókò náà
  - Bá àwọn ìṣòwò mìíràn tàbí àwọn ìjọ ìṣòwò sọ̀rọ̀, Béèrè nǹkan tí wọ́n ń ṣe láti gbaradì.
  - Ṣe ètò ohun tó bá ṣiṣẹ́ fún ọ.
  - Àdáṣe – gẹ́gẹ́ bíi àdáṣe nípa iná, ìwọ yóò gbaradì sílẹ̀ díẹ̀ sí tí ọ bá mọ ohun tí wàá sọ àti ṣe.
  - Darapọ̀ mọ́ àwọn alábàákẹ́gbẹ́ ìdáhùn sí ìṣíwọ̀lú ní agbègbè rẹ. Wọ́n máa ń pèsè àtìlẹ́yìn lórí ẹbí, òfin, owó, àti àwọn ìfiyèsí nípa ohun ìgbéróyìnjáde tí àwọn aṣojú ìṣíwọ̀lú bá wá sí ibi ìṣòwò rẹ.
- Ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn òṣìṣẹ́ rẹ láti máa sọ̀rọ̀ sí àwọn aṣojú ICE
  - Ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn òṣìṣẹ́ rẹ láti má gba àwọn aṣojú ICE láyé láti wọlé sí inú ibi-iṣẹ́ rẹ.
  - Òṣìṣẹ́ kan lè sọ pé, "mi ò lè fún ọ ní ìyọ̀nda láti wọlé, Ọ gbọ́dọ̀ bá agbanisíṣẹ́ mi sọ̀rọ̀."
  - Ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún gbogbo àwọn òṣìṣẹ́ rẹ láti máa sọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn aṣojú ICE. Tí àwọn aṣojú ICE bá ní àwọn ìbéèrè tàbí ìbẹ̀wẹ̀, àwọn òṣìṣẹ́ ò gbọ́dọ̀ sọ ohunkóhun, tàbí wọ́n lè sọ pé, "Ọ kò ní ààyè láti wọlé. Bá agbanisíṣẹ́ mi sọ̀rọ̀."
- Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ!
  - Àwọn agbanisíṣẹ́ ní ẹ̀tọ́ nígbà tí ICE bá lọ sí ibi ìṣòwò wọn. Kìí ṣe gbogbo ìgbà ni àwọn aṣojú ICE ní ẹ̀tọ́ láti wọlé sí ibi ìṣòwò rẹ, dá àwọn òṣìṣẹ́ rẹ dúró tàbí fi wọn sí àtìmọ́lé, tàbí gba àwọn ìwé àkọsílẹ̀.
  - Ṣiṣẹ́ pẹ̀lú ẹgbẹ́ àwùjọ kan tàbí òfin láti ṣètò ìdánilẹ́kọ̀ọ́ "Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ" kan fún ìwọ àti àwọn òṣìṣẹ́ rẹ àti kí ọ sì sanwó àkókò tí àwọn òṣìṣẹ́ lò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà.
  - Ní àgbóyé ìyàtọ̀ láàárín àwọn ìwé-àṣẹ ilé-ẹjọ́ àti ti àwọn alákòóso
    - Adájọ́ gbọ́dọ̀ buwọ́lù ìwé-àṣẹ ilé-ẹjọ́ àti kí ó sì wà ní àkọsílẹ̀ lórí rẹ̀ pé "Ilé-ẹjọ́ Agbègbè U.S." tàbí Ilé-ẹjọ́ Ìpínlẹ̀ ní òkè rẹ̀.
      - Adájọ́ ìpínlẹ̀ tàbí ti ìjọba àpapọ̀ ló máa ń buwọ́lù ìwé-àṣẹ ilé-ẹjọ́.
      - Ìwé-àṣẹ ilé-ẹjọ́ lè fún àwọn agbófinró ní ààyè láti wọlé sí àwọn ààyè aládàáni bíi ilé rẹ, tàbí wíwá inú ọkọ̀ rẹ.
      - Láìsí ìwé-àṣẹ ilé-ẹjọ́, àwọn aṣojú ICE nílò ìyọ̀nda rẹ láti wọlé sí àwọn agbègbè aládàáni ní ibi ìṣòwò rẹ.
      - Fún àpẹẹrẹ: Ìwé-àṣẹ Ìfiòfinmú, Ìwé-àṣẹ fún Ṣíṣe Àwárí
    - Òṣìṣẹ́ DHS ló máa ń buwọ́lù ìwé-àṣẹ alákòóso, kìí ṣe adájọ́.
      - Èyí ò fún ICE tàbí CBP ní àṣẹ kankan láti béèrè ìwọlé sí àwọn agbègbè aládàáni ibi-iṣẹ́ tàbí ilé.
      - Fún àpẹẹrẹ: Ìwé-àṣẹ fún Ìfiòfinmú Àjèjì, Ìwé-àṣẹ Ìyọkúrò/Lílé Ẹni Kúrò Nílùú

# ÀWỌN AGBANISÍṢẸ́: Bí a ṣe lè gbaradì fún àbẹ̀wò ICE

## Lásíkò àbẹ̀wò

- Farabalẹ̀! Sọ fún àwọn òṣìṣẹ́ rẹ kí wọ́n farabalẹ̀. Má ṣe sálọ sí ọ̀nà àbájáde. Èyí yóò jẹ́ kí àwọn ohun-kan burú síi nítorí pé àwọn aṣojú ICE lè sọ pé ó ṣeéṣe pé àwọn ènìyàn tó ń sálọ ti tàpá sí àwọn òfin ìṣíwọ̀lú.
- Tí àwọn aṣojú ICE bá gbìyànjú láti wọlé sí inú agbègbè aládàáni, ọ lè sọ pé: "Ibí jẹ́ agbègbè aládàáni. Ẹ kò lè wọlé láìsí ìwé-àṣẹ ilé-ẹjọ́ tí adájọ́ buwọ́lù. Ǹjẹ́ ẹ ní ìwé-àṣẹ ilé-ẹjọ́?"
  - ÀMỌ̀RÀN ṢÓKÍ: Láti ṣàfihàn pé àwọn agbègbè kan jẹ́ aládàáni, ṣàmì sí wọn pẹ̀lú ààmì "Aládàáni", jẹ́ kí àwọn ilẹ̀kùn náà wà ní pípadé tàbí títìípa, kí ọ sì ní ìlànà pé àwọn olùbẹ̀wò àti ará àwùjọ ò leè wọlé sí àwọn agbègbè wọ̀nyí láì gba ìyọ̀nda.
- Tí ICE bá fi ìwé-àṣẹ alákòóso tí orúko òṣìṣẹ́ kan wà lórí rẹ̀ hàn ọ́:
  - Ọ kò ní láti sọ bóyá òṣìṣẹ́ náà wà ní ẹnu iṣẹ́ lọ́jọ́ náà tàbí kò sí lẹnu iṣẹ́.
  - Ọ kò ní láti mú àwọn aṣojú ICE lọ bá òṣìṣẹ́ tí orúkọ rẹ̀ wà lórí ìwé-àṣẹ náà (kódà tí ó bá wà ní ibi-iṣẹ́ nígbà náà).
- Má ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn aṣojú ICE láti to àwọn ènìyàn lẹsẹsẹ pẹ̀lú ipò ìṣíwọ̀lú wọn tàbí orílẹ̀-èdè tí wọ́n ti wá.
- Máa wo àwọn aṣojú náà láti ríi bóyá wọ́n ń tẹ̀lé ohun tó wà ní àkọsílẹ̀ sínú ìwé-àṣẹ náà.
- Tí ìwọ tàbí òṣìṣẹ́ kan bá ńfẹ́, ṣe àkásílẹ̀ fídíò ohun tí àwọn aṣojú ICE bá ṣe ní ibi-iṣẹ́ rẹ. Ọ lè ní àǹfààní láti ṣàfihàn pé àwọn aṣojú yìí tàpá sí àwọn ẹ̀tọ́ rẹ tàbí ẹ̀tọ́ àwọn òṣìṣẹ́ rẹ.




## Lẹ́yìn àbẹ̀wò

- Ṣe àkọọ́lẹ̀ tàbí àkásílẹ̀ àwọn ohun wọ̀nyí lẹ́yìn tí ICE bá ti lọ:
  - Iye àwọn aṣojú ICE tó wá (tó wà nínú ilé àti ní ìta)?
  - Báwo ni àwọn aṣojú ICE náà ṣe múra? Báwo ni wọ́n ṣe ní nǹkan ogun sí?
  - Ṣé àwọn aṣojú náà jẹ́ kí ìwọ tàbí àwọn òṣìṣẹ́ rẹ gbàgbọ́ pé ẹ kò lè ṣípò tàbí kúrò?
- Ṣe àwọn aṣojú náà hùwà sí ẹnikẹ́ni lọ́nà àìtọ́? Tí ó bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ni, bíi báwo?
- Fi tó ẹgbẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ létí, tí ó bá ṣeéṣe.
- Tí ICE bá fi ikankan nínú àwọn òṣìṣẹ́ rẹ sí àtìmọ́lé, béèrè ibi tí wọ́n mú wọn lọ lọ́wọ́ àwọn aṣojú ICE. Àlàyé yìí ó ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ẹbí òṣìṣẹ́ náà àti agbẹjọ́rò rẹ láti ṣàwárí ẹni náà.
- Ṣe ìfisùn ìgbógun náà.
- Tí enìkan bá wà ní ìdádúró sí ìhámọ́, wo Ètò Ayélujára ICE fún Olùṣàwárí Ẹni tó wà ní Ìhámọ́ ní locator.ice.gov.

### Àwọn ohun-àmúlò

- Ṣàwárí àkókún àtòjọ àwọn ohun-àmúlò ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ ní ọ̀nà àsopọ̀ ayélujára: nyic.org/kyr
- Fún àlàyé díẹ̀ sí lórí àwọn ẹ̀tọ́ olùṣíwọ̀lú àti bí ọ ṣe lè dáàbòbo àwọn àwùjọ rẹ, ṣàbẹ̀wò sí Iṣẹ́-àkànṣe Ìgbèjà Olùṣíwọ̀lú ní ọ̀nà àsopọ̀ ayélujára yìí: immigrantdefenseproject.org
- Fún àlàyé díẹ̀ sí lórí àwọn ohun-àmúlò fún àwọn àwùjọ olùṣíwọ̀lú, ṣàbẹ̀wò sí Ibùdó Òfin Ìṣíwọ̀lú Orílẹ̀-èdè ní ọ̀nà àsopọ̀ ayélujára yìí: nilc.org/resources/
- Tí ọ bá nílò ìrànwọ́ pẹ̀lú ẹjọ́ rẹ tàbí ní àwọn ìbéèrè lórí ìṣíwọ̀lú lápapọ̀, pe Ọ́fíìsì fún Ago ìpè ìrànlọ́wọ́ ẹlẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ Àwọn Ọmọ-ìlú Amẹ́ríkà Tuntun ní 1-800-566-7636 tàbí ṣe àbẹ̀wò sí ààyè wẹ́ẹ̀bù wọn ní ọ̀nà àsopọ̀ ayélujára: dos.ny.gov/office-new-americans